WEEKS 44&45
Kongi WK 44
7 18 36
Wk 45
2 19 38
Asiko BK WK 44
3 15 25 37
Wk 45
11 21 33 55
Ross Wk 44
22 & 49
WK 45
35&45

# Imole Owuro

ESIN ORO WA: IMỌLẸ DE OKUNKUN PARADA!

SAMCO OF NIGERIA
WK 44
NAP 23 32 54
Perm 23 32 37 54 55
My Address ?
Not nessesary.
Always meet me in
Imole Owuro
Every Saturday
4 12 32

Independent Paper Vol. XV NO 797 SATURDAY MAY 28, – FRIDAY JUNE 3, 1977 10K. (KOBO MEWA)

31 MAY 1977

# EGUNGUN TU OLUJOSIN KA NINU ṢOOSI

RUKERUDO ṣẹlẹ ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹẹdogun oṣu yi nigba ti ọpọlọpọ egungun ati ọmọlẹhin wọn jo wọ inu Ṣọọṣi kan nilu Eko ti nwọn si da awọn ero inu Ṣọọṣi na lojuru.

Irohin fi ye wa pe, pẹlu jagidijagan ni awọn egungun na fi wọ ile ijọsin Ijọ Onitẹbọmi Kinni ni Abule Okuta, Bariga nilu Eko.

Gẹgẹ bi a ti gbọ, iṣẹlẹ na ṣẹlẹ ni aarin agogo mẹrin si marun irọlẹ ni akoko ti apa kan ninu ọmọ Ijọ na nkọ ẹkọ itẹbọmi lọwọ.

Irohin sọ pe pẹlu igo ọti ati ofifo igo ni ọwọ wọn ni awọn egungun na pẹlu awọn ọmọlẹhin wọn ja wọ inu ile ijọsin na ti nwọn si bẹrẹ si i fi ijoko inu Ṣọọṣi na lu ara wọn, nwọn si fọ igo ọti ati ofifo igo ti nwọn ko lọwọ silẹ ninu Ṣọọṣi na.

Irohin fi kun un pe, nṣe ni ọti bẹrẹ si i run yankan ninu Ṣọọṣi na ati lori gbogbo ijoko ti o wa ninu rẹ.

A gbọ pe ninu rogbodiyan na, giloobu ina lẹntiriki mẹta ni o fọ ninu Ṣọọṣi na, obinrin kan si fi ara pa diẹ.

Ọgbẹni S. O. Lawal ti iṣe oludari Ijọ Onitẹbọmi na, sọ fun onirohin wa pe, igbakeji ti iru iṣẹlẹ bẹẹ yio ṣẹlẹ si Ijọ oun niyi. O ni ni deede iru akoko yi ni nwọn dan iru rẹ wo ni ọdun ti o kọja.

Ọgbẹni Lawal fi kun un pe nigba ti oun nṣe akitiyan lati dari awọn egungun na gba ọna ibomiran lọ, nṣe ni ọkan ninu wọn gun oun l'ọbẹ lẹhin.

A gbọ pe Ọgbẹni Lawal ti lọ fi iṣẹlẹ na to awọn Ọlọpa leti ni Papo Pedro.

## Gende lu gende pa nitori Obinrin?

IROHIN lati ilu Ijẹbu-Ode ni Ipinlẹ Ogun fi ye wa pe, nwọn ti lu ọkunrin kan pa ni Ijẹbu-Ode nitori obinrin orekelẹwa kan.

Gẹgẹ bi irohin ti wi gende meji ni nwọn sọ pe nwọn nba ara wọn ja nitori obinrin na, ti nwọn si nfi ọbẹ ja ati ohun ọṣẹ miran.

Siwaju si i, a gbo pe ninu ijakadi na ni ọkan ninu awọn onija na ti wọn pe orukọ rẹ ni Clninatu Nwobilor ti ṣubululẹ ti o si daku.

A gbọ pe nihin ni nwọn ti sare gbe ọkunrin na lọ sile iwosan Ijẹbu-Ode fun itọju.

Bakanna ni a gbọ pe ẹnikeji rẹ ti oun na farapa, gba ọna ọdọ awọn Ọlọpa ilu na lọ ti o si sọ fun wọn pe, okunrin kan ti nwọn npe ni Chinatu Nwabi-

(Woju Ewe Kẹjọ)

## Gambari ka Adajo lehin nile ejo?

OJU Adajọ Ibilẹ Onipo Keji nilu Ibadan, Oloye Y. B. Ogundipẹ, ri aburo iku ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹtalelogun oṣu karun ọdun yi nigba ti ọkunrin Gambari kan wọ ile ẹjọ rẹ lojiji ti • si fa ọbẹ yọ si Adajọ na lati gun un pa.

Gẹgẹ bi irohin na ti lọ, a gbọ pe jẹjẹ ni Adajọ na gori aga idajọ rẹ ni deede agøgo mẹsan abọ owurọ lati maa ba iṣẹ oojọ rẹ lọ. A gbọ pe bi o ti fẹ bẹrẹ iṣẹ ni ọkunrin kan ti o wọ aṣọ daradara wọ ile ẹjọ na wa lai fọtape, o fa ọbẹ yọ, o si bẹrẹ si i kigbe ni ede Hausa pe'': chigabba, chigabba''.

Irohin sọ pe, nihin ni ọkunrin na ti fa ọbẹ yọ ti o si morile ọdọ Adajọ na lori aga rẹ. Nihin ni awọn ero inu ile ẹjọ ati awọn akọwe ile ẹjọ pẹlu oṣiṣẹ miran ninu ile ẹjọ na ti bẹrẹ si i sa hilahilo lati gba ẹmi ara rẹ la.

Ki a to ṣẹju pẹu gẹgẹ bi a ti gbọ, ọkunrin na ti kan Adajọ lara. Adajọ ko r'ibi sa gba lọ mọ, ni ijakadi kirakita ba ṣẹlẹ laarin awọn mejeeji.

Irohin sọ pe nihin ni ariwo ''Ẹ gba ni o ! Ẹ gba ni o !'' ti gbilẹ kankan ki Adajọ na to r'ẹni gba a silẹ.

(Woju Ewe Kẹjọ)

## Apprentices Wanted

LEARN to become a successful printer; learn on modern machine with modern tecnique.

Parents, don't waste the time of your fresh Primary Six & Modern III School leavers; send them to learn modern printing, Ma— chine operating and Book-binding from us. Apply personally today.

The Works Manager,
(Imọlẹ Owurọ)
N4/496B Yemẹtu Aladorin,
Ibadan:



ALHAJI S. IṢOLA
Alakoso Hasbunalau Records)

# ATIORO OMO ATIALA

## Itan Eko ati omi (3)

GEGẸ bi nwọn ti nwi,
Nwọn ni,
Omi oniyọ ni okun
Ti nwọn nmu;
Nwọn ni:
"O mu haihai",
"O dabi itọ ẹṣin",
"Ko dara iwẹ",
"Ko dara l'ọfun",
"O nhu ni n'ikọ"
"O nya ni n'igbẹ",
Oniruuru awawi ni
A ngbọ lori
Ọrọ omi Eko yi
Ti nwọn tori ọrọ yi.
Ti nwọn pe ni
"Wọnyọsi i omi"
Nitori, bẹẹ gẹgẹ ni
Nwọn npe e
L'oju ẹni t'o nr'Eko
Lọpọlọpọ igba.
Eyi l'o wa mu wa ranti
Ohun t'ara Eko nsọ
N'ijọ ọjọsi
T'aṣọ titun wọ Eko;
Aṣọ eṣubeleke
Ti nwọn npe ni



"Wọnyọsi i";
Aṣọ gbese
Ti nwọn nwọ kalẹ.
Nigba t'o wa ya
T'omi ko si l'Eko
Ti nwọn nmu
Omi oniyọ
Ti nwọn tun pe ni
"Wọnyọsi i",
Mo wa ro arojinlẹ
Pe, "Wọnyọsi i"ti
Nwọn kọ pe l'akọkọ,
Oun l'o tẹna
T'o fa ekeji!
Mo wa joko pẹsẹ,
Mo bẹrẹ si i ronu;
Mo ro o siwa,
Mo ro o sẹhin
Mo ni
Aṣẹ nitootọ;
Orin nii ṣaaju ọtẹ!
Mo ni dajudaju,
Ara Eko l'o pe ogun,
T'ogun fi ya ile wa,
T'o wa ba gbogbo wọn;
Awọn l'o f'ẹnu pe ọtẹ,
T'ọtẹ yale wa lẹsẹkẹsẹ;
Ọtẹ ọhun yale wa,
Nwọn ko le le ọtẹ lọ;
Nwọn wa nṣaroye
Pe, awọn ko gbadun!
Mo wa pinnu pe,
Laiṣawawi,
Lai f'ọrọ bọ'po bọyọ,
Ani lai nii ṣeke,
"Wọnyọsii" akọkọ
L'o tun bimọ
T'o njẹ Wọnyọsi i;
"Wọnyọsi i" aṣọ
L'o dẹhinbọ t'o bi
"Wọnyọsi i" omi.
Nigbayi ni mo wa ranti
Pe, a ti nsọ ṣaaju
Pe, k'a ṣọra
Nibi ohun gbogbo
Ti a ba nwi;
A nkilọ ọran
Pe, k'a ṣọra
Ninu ọrọkọrọ.
A kilọ pe,
K'a ma daṣa
Ti ko nilaari,
K'a ma fi
Ẹnu jaraba ara wa;
A kilọ pe,
B'aṣa dida
Ko ba wọ,
K'a ma wulẹ d'aṣa.
Mo ni
Bi a ko ba le sinmẹdọ,
Ti a ko le ko
Ahọn ẹni duro;
K'a kuku maa sọ
Ohun t'o ba dara si
Ara wa gbogbo;
K'a ma tori aṣa dida,
K'a ma fa
Ara wa sinu adanwo
Abọde Wọnyọsi i ree o
Ẹnyin ẹlẹgbẹ wa.
Ati ara Sokoto,
Ati ara Enugu;
Ati ara Bendel,
Ati Kwara l'Oke,
Paapaa, ẹnyin
Oniṣowo ilu,
Ẹ maa wo
Orukọ rere
Lati maa fi gbe
Iṣẹ nyin ga
Nitori:
Ẹnyin Oniṣowo ni
Ọdada enia
Ti i da gbogbo rẹ silẹ,
Bi a ba si r'enia
T'o kọ ti ko gbọ;
Ẹ jẹ ki
Iru won ranti
Pe, b'o ba dele tan,
Ati iwọ,
Ati aya rẹ,
Ati ọkọ rẹ,
Ati ọmọ rẹ,
Ati gbogbo wa ni
Yio jọ yọ si l'ara.
Njẹ mo nbẹ ọ o
Iwọ Ọlọrun Ọba
T'o d'aiye
Ati ọrun gbogbo:
A ti rubọ s'omi,
Omi ko ni ipa.
K'o fi tun ara rẹ ṣe;
A ti ṣetutu titi,
Gbogbo oriṣa l'o kuna;
Gbogbo enia
Ti i fa ojo gbiyanju,
A ko r'ojo mu.
A ro ekuru, ro ọọlẹ
Gbogbo rẹ ko wulo
Ara Eko bọ ẹegun,
Nwọn bọ Ooṣa,
Ara Ibadan bọ Oke,
Oloolu gbe ẹbọ,
Ara Ogbomọṣọ
Ko dakẹ
Nwọn ṣe kisa
Nwọn si bọ iwin;
Ijẹbu bọ tire
Bẹẹ l'Ekiti.
Gbogbo enia dudu
L'o pamọpọ
Nwọn ke pe
Baba t'o ṣe wọn.
Gbogbo rẹ ko l'ere kan
Gbogbo rẹ
L'o ja buẹbuẹ,
Nṣe l'o ndikun wahala.
Mo wa kigbe pe Ọ,
Iwọ Adaniwaiye;
Ranti pe
Iṣẹ ọwọ Rẹ lawa iṣẹ
Ma ṣe wo
Iwa t'a nhu:
Nitori a ti ṣe Ọ jinna.
Ṣugbọn nitori ti
Mo ti fi
Gbogbo ọrọ yi kọ
Orukọ Rẹ l'ọrun;
Lati igbayi lọ;
Ati ọwọn omi,
Ati ọwọn ojo,
Ati ajakalẹ arun,
Ati ọwọn ounjẹ,
Dakun,
Ba ni mu
Ọwọ rẹ duro
Ni ilẹ wa.
Bẹẹ ni ki o jẹ k'o ri
l'ẹsẹkẹsẹ
ỌLỌLA ATIORO

# Ara Asa yari mo ara Ilorin lowo

AWỌN enia ilu Asa ati More ni Ipinlẹ Kwara, ti yari patapata pe awọn ko fẹ ẹnikẹni ti ki ba ṣe ọmọ ilu awọn gẹgẹ bi Olori ilu na mọ lati igba yi lọ.

Awọn enia na sọ pe nitorina, ki gbogbo Olori ti awọn ara Ilọrin yan sọdọ awon yara palẹ wọn mo kuro nibe kiakia, ki Ijọba si fi ọwọ si yiyan ọmọ onilu sori itẹ ilu rẹ.

Ni ilu Ilọrin ni awọn Alaga Kansul Ilu meieeji Ọgbẹni U. B. Mohammed ati Ọgbẹni D. A. Akinọla ti pe ipe na laipẹ yi nigba ti nwọn nba awọn oniwerohin sọrọ.

Siwaju si i, awọn Alaga na nfẹ ki aṣoju tiwọn na wa ninu Igbimọ igberiko Ilọrin ti nwọn ṣẹṣẹ dasilẹ.

Ninu ọrọ wọn na, awọn enia na sọ bi awọn enia awọn ṣe ti kọ oniruuru iwe ẹbẹ si Ijọba Ipinlẹ Kwara pe awọn ko fẹ ajeji mọ lati jẹ Olori ilu awọn; nwọn si ran Ijọba leti pe, o ti ṣe iru rẹ fun agbegbe Igbira nigbakan, nipa mimu ajeji kuro ni ọdọ wọn nigbti nwọn ko fe wọn mọ.

Nwọn ni awọn Olori ilu ti o wa ni Asa ati More bayi jẹ ibatan Ọba Ilọrin tabi ti awọn Balogun ilu na.

Nwọn ni yiyan ajeji gẹgẹ bi Olori adugbo si Asa ati More ti yiyan wọn sinu Igbimọ agbegbe Ilọrin, lai jẹ pe awọn oloye ibilẹ ilu wonyi gan-an l'o wa nibẹ, jẹ ohun ti o mu ki atunto eto Ijọba ibilẹ jọ fifi enia sabẹ ajaga isinru.

# Isin Iranti waiye fun Ajibike Opaleke

NI aipẹ yi ni nwọn ṣe isin iranti fun ọkan ninu ọga ile iṣẹ akoso eto ẹkọ ni Ipinlẹ Kwara, Iyaafin Titilayọ Ajibikẹ Ọpaleke ẹni ti o jalaisi ni ọjọ kẹtadinlọgbọn oṣu kẹta ọdun yi lẹhin aisan ranpe kan ti o ṣe e. Ọdun marundinlogoji ni o lo l'aiye.

Ọna meji ni nwọn ti ṣe isin iranti na. Nwọn ṣe ni Iyẹru-Ọkin African Church nilu Ọfa ati Emmanuel Baptist Church nilu Ilọrin

Nigba aiye rẹ, Oloogbe na ti ṣe Olori ile ẹkọ Girama fun awọn obinrin Ihina Govement Girls Secondary ni ilẹ Igbira ki o to bọ si ile iṣẹ akoso eto ẹkọ ilu Ilọrin.

Ọmọ Dara ni Ile Idi Odu nilu Ipẹẹ ni oloogbe na iṣe, nibẹ ni o si ti bẹrẹ si i kẹkọ. Bakanna ni o kẹkọ ni Yunifasiti Naijiria nilu Nsuka, Yunifasiti Ahmadu Belo ati Yunifasiti Eko.

Ninu isin iranti wọnyi, Alufaa S.O. Fọlayan ti Ọfa ati Alufaa G.A. Adeọla sọrọ iyin pupọ ninu iwa oloogbe na l'enu iṣẹ ati ninu Ijọ Ọlọrun, nwọn si sọ bi o ṣe jẹ pe orileede Naijiria padanu ohun pupọ nipa iku oloogbe na.

Nigbana ni nwọn kesi olukuluku enia lati fi igbesi aiye rere ti oloogbe na gbe gẹgẹ bi oṣiṣẹ olootọ ati gẹgẹ bi olusin tootọ ṣe awokọṣe.

Ara awọn enia ti o wa sibi sin iranti na ni Oloye (Iyaafin) F.A. Adeṣiyun, D.A. Ologunde, Adajọ Ọlọla E.A. Adewuyi, Oloye T.A. Wuraọla ati bẹẹbẹẹ lọ

# Lawal Alagbe saisi

NWỌN ti kede iku Alaga Ẹgbẹ Ogbomọṣọ Shamusi-deen ti Ibadan, Ọgbẹni Lawal Alabe.

Aisan ranpẹ kan ni o ṣe oloogbe na ki o to ṣaisi ni ile iwosan Oritamefa (UCH), Ibadan ni ọjọ kẹrinlelogun oṣu kẹrin ọdun yi.

Ilu rẹ Ogbomọṣọ ni nwọn gbe e lọ nibi ti nwọn ti ṣe isin ikẹhin fun un gẹgẹ bi ilana ẹsin Islam ni agbo ile Onilu, Isalẹ Ilogbo ki nwọn to lọ sinku rẹ si itẹku awọn ẹlẹsin rẹ

(Woju Ewe Keje)

# ISORO-NIGBESI..

## IPADE (57)

Adeyẹmọ Ojẹrinde
ỌỌKU l'oni ọmọ Ejigbọjọ,
Ejiwande, Ilagbẹdẹ
Ọmọ ọlọkọ titun
Irẹmogun ọmọ Ayoyọ
Ti i j'Ejigbọjọ.
O ku ipade t'o kọja
O si ku alaye rẹ gbogbo
Ti o ṣe l'ori oṣo at'ajẹ
Ati gbogbo oloogun ika.
Ayinde! mo tun fẹ ki o jọwọ
Ki o ṣalaye ọrọ si i
L'ori bi nwọn ṣe nṣiṣẹ wọn
Nitori pe:
"Oṣo nbẹ, ajẹ nbẹ,
Oloogun ika nbẹ,
Emere nbẹ" nikan
Ni ohun gbogbo pata
Ti o sọ fun wa,
O si yẹ ki o ṣalaye
Bi nwọn ṣe nṣiṣẹ ọhun delẹ.
Lawuyi Ogunniran
Mo gbọ ohun ti o wi
Ọmọ Ajiṣegiri;
Ọrọ rẹ jọ mi l'oju,
O ṣe mi ni kayeefi.
O ni ki ng sọ fun ọ
Bi oṣo nbẹ,
Bi ajẹ nbẹ,
Bi oloogun ika nbẹ
Nitoripe:
Alakọwe nsọ fun ọ
Pe, ko si ohun ti i jẹ bẹẹ
Ni gbogbo ilẹkilẹ.
Mo si ti f'esi ọrọ
Pe, oṣo nbẹ, ajẹ nbẹ,
Emere ati oloogun ika nbẹ,
Mo ni nwọn nbẹ nilẹ yi,
Nwọn nbẹ nilẹ miran;
Nwọn nbẹ ni gbogbo aiye
Nwọn nbẹ nibigbogbo
Nwọn si nṣiṣẹ ika
Ni gbogbo ilẹkilẹ.
Lẹhin ti mo ti sọ eyi tan
O tun wa nbeere lọwọ mi
Pe, bawo ni
Nwọn ṣe nṣiṣẹ wọn
Nigba t'emi ki i ṣe oṣo,
Nigba t'emi ki i ṣ'ajẹ,
Nigba t'emi ki i ṣe emere,
Ti ng ki i ṣ'oloogun ika,
Bawo ni mo ṣe le sọ
Bi nwọn ṣe nṣiṣẹ wọn?
Adeyẹmọ Ojẹrinde
Ki l'o de too le so 'di
Ọmọ Ejigbọjọ?
Ki l'o de too le sọrọ yi
Ọmọ Ayoyọ?
Ṣe bi o maa nhuwa
Bi ẹni pe,
Ko si 'hun too le mọ ni
Tabi iwọ kọ ni,
Ọmọran ti i mo oyun igbin
Ninu ikarahun?
Tabi iwọ kọ ni
Apitan-ma-pa t'ana
Ti i dana itan
Bi ẹni t'ọrun bọ wa sile aiye?
Tabi o ti gbagbe
Igba t'a nṣe "Bọmọ o' ba tan"
T'o nle furukọkọ
Pe, o mọ ohun gbogbo?
Tabi o *ko* ranti
Igba ti o nfapajanu
Pe, iru nyin ti koja
Ẹni ti a le fi itan demọlẹ?
Ki l'o wa de
Ti o ko le pitan delẹ
Bi oṣo ṣe nṣe oṣo
Ti o ko le pitan
Bi ajẹ ṣe npa eniyan?
Ti o ko le sọ idi itan
Bi oloogun ika
Ti nṣiṣẹ ika wọn
Ati bi awọn emere
Ṣe ndan nkan wo?
O wa tan n'bi ko tan Ọmọ Ejigbọjọ
Kutakuta rẹ wa pin tabi ko pin
Bẹẹ iwọ l'o maa nsọrọ
Pe, itan ti a ba npa
Ti a ko ba le rọ ọ,
Oju ni i ti ni?
Lawuyi Ogunniran
Bẹẹ ọlọgbọn l'o npe 'ra rẹ bayi
Ọmọ Ajiṣegiri?
Ẹru ko si ba ọ rara
Lati parọ mọ iru mi
Nitori pe a jọ npotobo ẹnu?
L'ọjọ wo ni mo sọ fun ọ
Pe, mo mọ ohun gbogbo?
Tabi ẹni kọ ha ni
Mo pitan fun ọ
Pe, ọgbọn ko ṣe t'ẹni kan?
Mo ni, ọmọde gbọn,
Agba na gbọn
L'a fi da ode isalaye?
N'ijọ wo ni mo waa sọ
Pe, ko s'iru mi?
Ki a tilẹ wa sọ pe
Mo pe ara mi bẹẹ;
Ṣe bi iwọ l'o maa nsọ
Pe, bi o ba ri eniyan
Ti yio sọ idi aiye,
Iwọ na yio sọ idi ọrun,
Ṣe iwọ wa le pitanpitan
Ki o sọ b'isalu ọran ṣe ṣẹ?
Nitorina, ọmọ Ajiṣegiri:
Mo mọ pe oṣo nbẹ ni
Ng ko mọ b'oṣo ṣe e ṣiṣẹ;
Mo mọ p'ajẹ wa
Ati Oloogun ika
Mo si mo p'emere nbẹ ninu ilu
Ṣugbọn ng ko le sọ
Bi nwọn ṣe nṣiṣẹ wọn.
Ṣugbọn mo fẹ ki o ye ọ
Pe, gbogbo ẹni pata
T'o ba nsọ pe, w.n ko si,
Ma da wọn lohun ọjare
Ọgbọn inu wọn l'o kere yeye.
B'o o r'ọmọwe to wosunsun
T'o sọ pe ko ṣ'ajẹ nile duniyan,
Ma da a wọn lohun ọjare
Irọ ti nwọn kọ
Ni nwọn npa fun ọ.
Mo si mọ idi ọrọ
Ti nwọn fi nsọ pe,
Oṣo at'ajẹ ko si nibikan.
Ibi ti mo deduro ree
Baba Kafilatu.

**Confidence Nap**

**12x**

**21**

**42**

**30**

**12 & 32**

IWE IGBAẸLODE
DARA PUPỌ.
RA TIRẸ NIBẸ
1. Iwe gbogbo Agbo Ọmọde ati Agba 20k
2. Kurani ọgọta esu ni ede Yoruba ₦10 Esu kan (50k)
3. Yasin ni Yoruba ati Isawaka 50k
4. Zabura ati Itumọ (₦1)
5 Zabura Yoruba (₦1)
6. Iwe Aiye Akamara (₦1)
7. Iwe Eniaṣoro (₦1) Adedẹwẹ (50k)
8. Iwosan Ajẹbidan Ogun enia dudu (₦6); Kekere (50k)
9. Iwe ala ni nla (₦2)
10. Kekere (50k)
11. Iwe Oogun iwosan (₦2.50) Kekere (75k)
12. Itan Anabi ati Yisa (₦1)
13. English Hausa Yoruba & Ibo Registered No 410 (50k)
FI OWO ATI STAMP (5k) RANṢẸ SI:
(1) Alufa Yisa Igbaẹlode N2/394a Odoye Adeọyọ Rd, P. O. Box 3365, Mapo—Ibadan.

(2) Alufa Igbaẹlode, Mọṣalaṣi Idi. Iṣin St Isalẹ Koto P. O. Box 17. Ilọrin

# Akédé ọ̀nà Ìyè



WOLI S. I. OWOẸYẸ
Oniwaasu Naa.

# Olotito ntan lo ninu awon omo enia (4)

## Lati Owo Woli S. I. Owoeye

"BI awa ba jẹwọ ẹṣẹ wa, Oloọtọ ati olododo li Oun lati dari ẹṣẹ wa ji wa, ati lati wẹ wa nu kuro ninu aiṣododo gbogbo. Bi awa ba wi pe awa ko dẹṣẹ, awa mu Un li eke, Ọrọ Rẹ ko si si ninu wa"; I Johanu 1;9-10.

Ninu aiye ni ode oni, alaiṣootọ ati alaiṣododo l'o pọjulọ. Taa ni enia na ti ko ni iwa aiṣododo lọwọ ri yala ni ọna kan tabi ọna miran?

Njẹ kini ohun na ti o le maa sọ ni di alaisododo l'aiye ode oni? Iwa ẹni ni i sọ ni di alaiṣododo; aiṣododo si bẹrẹ nibi ọpọ iwa ati iṣe wa ti a ko ka si.

Fun apẹẹrẹ: ọpọ igba ni ẹlomiran maa nni nkan rere lati ṣe ninu ile ti o jẹ pe bi o ba sọ nibi iṣẹ Ijọba pe oun fẹ ṣe nkan eyẹ, ki nwọn fun oun laaye, nwọn ko ni i fun un l'aaye.

Nitorina, yio maa wa irọ ti yio pa lati fi gba aaye.

Bakanna ni ihuwasi enia miran a maa mu un parọ. O le ti rin irin agbere tabi irede oru lọ; ki o wa sun kọja akoko ti o yẹ ki o lọ sibi iṣẹ.

Nigba ti o ba de ibi iṣ;, ko ni i ṣe e ṣe fun un lati sọ pe nitori irin irede oru ti oun rin lọ ni o mu ki oun sun gbagbe nipa eyi ti oun fi pẹ lati de ẹnu iṣẹ; irọ nla kan ni yio pa ki o le gba ara rẹ silẹ.

Ẹnyin ọmọ enia, bayi ni irọ, eke ati iwa aiṣododo gbogbo yi ile ati ọna wa po l'orilẹ—ede aiye tobẹẹ ti awọn ọmọ wa ti o ṣẹṣẹ ndagba ko tilẹ ri ẹko ododo ati otitọ kọ lara wa bikoṣe pe ninu iwa aiṣododo wa ni awọn na ndagba si.

Iwọ ati emi ni ·Ọrọ Ọlọrun nba wi l'oni pe, o yẹ ki a gbe igbesi aiye ododo ki a si maa fi ẹṣẹ awọn ọmọ wa le ipa ọna na; nitoripe gbogbo aiṣedeede pata ni ẹṣẹ, ẹṣẹ yi si ni idena ti o maa nmu ki adura wa dabi ẹni pe ko gba.

Nitoripe, ẹṣẹ da bi ẹni ti o wọ ẹwu irin ti o wa nbu omi si ara pe oun nwẹ eeri ara oun danu. Njẹ omi na ha le wọ ọ l'ara lati ko eeri ara rẹ kuro niwọn igba ti ẹwu irin na nbẹ ni ọrun rẹ bi?

Nitorina ni ọrọ Ọlọrun ṣe nran iwọ ati emi leti l'oni pe, ninu ẹṣẹ aiṣododo ni a wa ninu aiye, eyi ti o pọndan—dan fun wa lati kọsilẹ bi a ba nfẹ ki adura wa gba, ti a nfẹ ri ojurere Ọlọrun, ti a si nfẹ jẹ ajumọjogun iye pẹlu ọmọ Rẹ Jesu Kristi.

Ṣugbọn ọna ti a le gba ri eyi ni ki a tara kọ ẹṣẹ silẹ l'oni ni otitọ ati ododo. Ki a jẹwọ ẹṣẹ wa fun Ọlọrun ki a le ri idariji gba.

Bi a ba wo oniruuru idaamu ti o maa nba idile, ẹgbẹ, ilu ati orileede aiye l'oni, a o ri i pe nipa ẹṣẹ ni.

Gbogbo ohun ti o ba jẹmọ agidi, ibinu odi, irinkurin, isọkusọ, iṣekuṣe, ijẹkujẹ, iwakiwa aigba Jesu Kristi gbọ gẹgẹ bi Olugbala araiye, ẹṣẹ gidigidi ni nipa eyi ti o jẹ pe bi ẹni ti nda iru ẹṣẹ na ko ba yipada kuro ninu rẹ, ko le ri Ọlọrun.

Bakanna ni ẹṣẹ amọ-Ẹlomiran yio mọ pe iru iwa kan ko dara ṣugbọn yio maa hu u. Iru awọn enia bayi ni i fi Ọlọrun Otitọ silẹ ti yio si maa wa ọlọrun miran kiri. Iru iwa yi a maa mu ki adura ẹlomiran di ẹṣẹ si i l'ọrun.

Fun apẹẹrẹ, iwọ ti o mọ pe, ẹṣẹ ni ole jija jẹ ti o wa dide lati lọ si ibugbe ẹlomiran lati ja a mọda kun inu aiye, Ẹlomiran yio ri otitọ nilẹ ṣugbọn yio maa gbiyanju lati yi i po, lole, njẹ ko ha ni di ẹru wuwo si ọ lọrun lati gbadura si Ọlọrun Otitọ pe, iwọ fẹ jade lati lọ jale nitorna, kii Ọlọrun jẹ ki ki o lọ layọ ki o bọ layọ?

Bayi ni adura maa njẹ ẹru wuwo lọrun ẹlẹṣẹ enia. Ẹni ti o ba wa lori otitọ ati ododo ni adura rẹ maa ngba, awọn si ni Ọrẹ Jesu Kristi gẹgẹ bi O ti wi pe, "Ọrẹ mi ni ẹnyin i ṣe bi ẹ ba nṣe ohun ti mo palaṣẹ fun nyin."

Ẹ ranti pe, ipilẹ ati opin Jesu Kristi ninu aiye jẹ lori otitọ ati ododo.

ADURA

Jesu! Yi mi pada si rere ki ng ma baa ṣegbe, Aamin.


## Wanted

APPRENTICES and advanced apprentices are wanted in our Printing Section.

Remuneration is very attractive. Bring your application by hand to the Manager:

NIGERIA NEW STATES CO:
18, Ọdunlami Street,
Lagos.



## NIGERIA NEW STATES CO.

Jẹ atẹwe asiko. Bi o ba fẹ tẹ oniruuru iwe Kalẹnda, Almanak ati bẹẹbẹẹ lo, Ile Iṣẹ wa ni:

18, Ọdunlami Street,
Phone 27017, Lagos.



## IWE ỌRỌ ỌLỌRUN

Fun anfani ẹnyin ti o ṣoro fun lati ri iwe mi yi ra ni ọkookan, mo ti ṣeto lati maa fi apapọ iwe na ṣọwọ si nyin ni aadọta Kọbọ (50k) pere.

1. ADURA AIYERAIYE
2. IBANIWI OLUWA
3. KINI ILE AIYE ṢE BAJẸ?
4. Ẹ JOWO ARA NYIN FUN OLUWA

Bi o ba ti fi Postal Order 50k ṣọwọ si mi, ng o fi apapọ iwe na ṣọwọ si ọ lagbara Oluwa, Fi owo ranṣẹ si:

Woli S. I. Owoẹyẹ
Box 1206,
Ibadan.

# Irohin Ni Onilujilu

## Ilu Eko

ADAJỌ ile ẹjọ Senior Magistrate ni Yaba Eko Iyaafin J. O. Obaro, ti ko lati gba iduro awon enia meje kan ti nwon fi ẹsun idigunjale l'ona Ikorodu ni Ipinlẹ Eko kan.

Awon odaran na ni: Andrew Okurebe (29) ti o jẹ Ṣoja, Isaac Nwogbe (27) ti o pe ara rẹ ni onisowo, David Okon (25) ti o pe ara rẹ ni Kọngilato, Johnson Emiasho, Tajudeen Aderokun (25) ti o jẹ dẹrẹba, Sunday Ajibade (26) ti o pe ara ni onisowo ati Dominic Eze.

Awon afẹsunkanni ka ẹsun si awon enia na ati mẹta miran ti o na papa bora, gbimopo da okunrin awakọ kan Lasisi Lamidi ti iṣe awako kan l'ona ni agogo mẹjo-abo alẹ ojo kokanla oṣu karun odun yi l'ona Ikorodu, won si gba moto Mercedes Benz rẹ nonba OY 834A ti iye owo rẹ jẹ ẹgbaaje Naira (₦14,000.00)

Bakanna ni nwon tun so pe, nwon ji opolopo oniruru agolo oda ti iye owo rẹ fẹrẹ to ẹẹdegbaarin Naira (₦6.964.00) ti ise eyi ti ile iṣe iṣowo BEWAC, Apapa.

Nwon ni awon odaran na dira ogun pẹlu ibon machine gun ni akoko idigunjale na.

Adajo ile ẹjọ na kọ si agbẹjoro okan ninu won l'ẹnu lati gba iduro awon odaran na. O di ojo kejidinlogbon oṣu keje odun yi ki nwon to tun farahan nile ẹjọ.

## Ilu Kano

IROHIN lati ilu Kano fi ye wa pe, o le ni ọsẹ marun bayi ti awọn enia ọpọlọpọ adugbo ni ilu na ko ti ri omi ẹrọ mu.

Ara awọn adugbo ti oran na kan julo ni: Ọna Ibrahimu Taiwo, Ọna Beirut, Fagge, Nasarawa ati bẹẹbẹẹ lo.

Ẹnikan fi ye wa pe, iru iṣẹlẹ bayi ki i saba ṣẹlẹ si ilu Kano; ṣugbọn a gbọ pe awọn Alaṣẹ nlakaka tati bori iṣoro na.

## Ilu Pota

IROHIN lati ilu Pota (Port-Harcourt) ni Ipinlẹ Ẹsẹ-odo fi ye wa pe ọmọde mẹta l'o jona ruuruu ninu ijanba ile jijo ti o ṣẹlẹ ni ọna Greek ni ilu na laipẹ yi.

Ọpọlọpọ ile l'o jona ati dukia ọlọkẹ marun (₦100,000.00) l'o ṣegbe ninu ijanba na. O le ni ẹgbẹrun enia ti o di alainilelori.

Irohin fi ye wa pe ohun ti o fa sababi ọrọ na ni ẹnikan ti o tan abẹla sile l'akoko ti nwọn mu ina lọ, ṣugbọn ti ina na ran mọ ile ti o fi di pe agba epo ti ri awọn kan gbesile ni adugbo na fi gbina. Awọn Ọlọpa ti bẹrẹ iwadi l'ori ọrọ na.

## Ilu Okitipupa

ADAJỌ Ile ẹjọ Senior Magistrate kan ni ilu Okitipupa, Ọgbẹni Babatunde Alonge, ti paṣẹ fun Ọba kan ni Ipinlẹ Ondo lati lọ gbe jẹẹ fun oṣu mejila bi ko ba fẹ lugbadi ijẹniya ofin.

Ọba na ni Ọloja Iyansan lẹba Irede ni Okitipupa.

Ọkunrin agbẹ kan ti o ba Ọba na dun oye lakoko ti itẹ Ọba na ṣofo, Ọgbẹni Richard Ogbe ni o pejo sile ẹjọ pe ki ile ẹjọ fi ofin de Ọba na nitori pe, lati igba ti o ti gori itẹ ni o ti nja oun logun, debi pe, o dẹ awọn Ọlọpa si oun lati fi ẹsun odaran kan oun.

Aiyedetisola

Commercial

Electrical

Store:

Will satisfy all your electronics needs at resonable prices

Call at

AN27&41 I.C.C STALL
AGODI GATE
IBADAN

## Akiyesi fun Onkawe

EYI ni lati kede fun gbogbo onkawe ti o ba nkowe "Ẹ GBỌ TEMI" si wa fun titẹjade, pe, ẹ gbodo maa kọ orukọ nyin ati ti Adirẹsi nyin tooto si ara iwe na.

Nitori pe, opolopo iwe ni a nri gba lati odo onkawe ti awon ti o ko won ko fi Adirẹsi won tooto si i l'ara.

Bakanna ni ẹlomiran yio kowe si wa lati ilu Eko, ṣugbon ti yio fi Adirẹsi awuruju si i pe lati "Bukuru" tabi "Ogbomoṣo" ni oun ti ko o.

Iru iwa yi poju lowo awon ti nkowe si wa, eyi ti o lodi si ilana iṣẹ wa.

A fe ki o ye olukuluku pe bi o ti wu ki oro inu iwe ti ẹ ko le to, a o fi tayotayo gba a yẹwo, a o si tẹ ẹ jade bi o ba yẹ, koda bi o jẹ pe awa paapaa ni oro na ba wi.

Nitorina bi a ba ri iwe kan gba ti ko tẹle ilana iṣẹ wa tabi ti ko ba mu ogbon dani; tabi ti ko ba le ṣanfani fun onkawe tabi ti oro inu rẹ ba lodi si ofin, a ko ni i tẹ ẹ jade

—OLOOTU

Yasin ati Isawaka

EYI ni lati kede fun ẹnyin onibara wa ti ẹ ti nkowe si wa lati ọjọ pipẹ pe, a ti ni Yaasin ati Isawaka ni ede Yoruba ati Wutuba rẹ.

Adura pataki ni fun Musulumi. 50k ni Ẹyọkan, ₦2. ni Dosinni rẹ.

Tete fi owo ranṣẹ si:-

1 Alufaa Igbaẹlode
N2/394A Odoiye
Adeoyo Rd,
P. O. Box 3365
Mapo, Ibadan

(2) Alufaa Igbaẹlode
Moṣalaṣi Idi Iṣin St;
Isale Koto,
P. O. Box 17
Ilorin

# Ẹ gbọ t'ẹmi

# Atunte itan Ogbomoso nko?

OLOOTU,

O ti to odun mẹwa bayi ti a ti gbo pe atuntẹ keji pelu atunṣe ti o yẹ lori Iwe Itan Ogbomoṣo wa lowo ẹni ti o kowe na, Baba wa Ọjọgbọn Nathaniel D. Oyerinde ẹni ti iṣe Otun Ṣohun Ogbomoṣo.

A tilẹ gbo pe Baba wa na ti pari gbogbo eto ti o yẹ l'ori rẹ nigbana ati pe yio jade laipẹ. Ohun ti o pilẹ fa atuntẹ keji ti awon enia nbeere fun titẹjade nigbana ni pe, ti akọkọ ko to ra.

Ṣugbon laipẹ yi ni irohin jade pe, Baba wa na jẹ ipe Ọlorun Ọba. Ṣugbon a ko mo ibi ti iṣẹ na deduro bayi: Bi o ti pari ni tabi ko ti i pari'

Bayi, Baba wa, opitan tooto, omowe pataki, ẹni nla ati olokiki ti o gbe ogo ilu *O*gbomoṣo yo, ti lo kuro ninu aiye yi. Ani, ẹni na ti a maa ndari ibeere si lori oro yi ti kuro laarin wa, a ko si le ri i mo!

Bawo ni a o ṣe mo ibi ti oro yi deduro? Bawo ni atuntẹ iwe Itan Ogbomoṣo yio ṣe jade? Bawo ni ogo, iyi ati ola iran wa ko ṣe ni i wo okunkun? Bawo ni awon iran wa ti nbo yio ṣe mo nipa awon baba wa ati bi nwon ṣe jẹ laarin iran Yoruba?

Nitorina, mo kesi gbogbo olufẹ Ogbomoṣo loba; ni Ijoye, sanmori, otokulu, talaka ati awon ti opon oro yi ba tun sunkan lati dide si oro na.

Emi ni,
Paul D. Onireti,
P. O. Box 73,
Ogbomọṣọ

## Mo ti mo Ololа Atioro!

OLOOTU,

MO lo oogun ti Atioro omo Atiala ko wa pe ki ẹni ti o ba fẹ mo oun ṣe.

Nigba ti mo toju ipin oju aayan, ipako omo eera, obi abata oloju merindinlogun tan, ti mo ṣe e bi Atioro ti ni ki a ṣe e, ti mo si lo o bi o ti ni ki a lo o, nigbana ni mo wa lo ka iwe Ewi Iwoyi ti mo si ka nipa ẹni ti Atioro iṣe.

Nwọn bi i ni ọdun 1912 ni ilu Abẹokuta Akintunde Ṣowumi ni oruko rẹ njẹ. O kowe ni ile ẹko Alakoberẹ Holytrinity Church School ni adugbo Ikereku ati i/e iwe giga Abẹokuta Grammar School. Nitorina, enia ni Atioro ki iṣe ẹiyẹ.

Emi ni,
Ganiyu Akinniyi,
Badia, Eko.

## Owon epo moto

OLOOTU,

ỌWỌN epo ti o nyọ ilẹ wa l'ẹnu yi ko dara rara nitoripe airi epo ra awọn onimoto nfa ọpọ iṣoro ba awon enia ilu nitoripe olukuluku ko le de ibi iṣẹ rẹ lasiko, o si tun mu ki owo moto ga si i.

Ki l'o le maa fa owon epo moto nigbagbogbo bayi?

Mo kesi Ijoba Apapo lati jowo ba mi ṣeto ki owon epo ma le ṣẹlẹ mo ni ilẹ wa.

Emi ni,
Raufu Oguntoye,
Ibadan.

## Otito koro

OLOOTU,

MO ri i ka ninu Imọlẹ Owurọ 4/5/77 labẹ akọle kan pe " Ibajẹ lasan ni". Nibẹ ni onkawe kan ti o pe ara rẹ ni Ajani Baba Kudi ti sọ pe oun lodi si alaye ti Olootu ṣe lori "Awọn wo ni olowo ojiji".

Bi Ajani Baba Kudi ko ba mọ wọn, ara awọn olowo ojiji ni Iṣọla Oyenusi, awọn onijibiti ati awọn ti o ndana kiri.

Ko yẹ ki o jẹ pe alaye iru awọn enia ti njẹ olowo ojiji, eyi ti Olootu ṣe yio maa bi Ajani Baba Kudi ninu rara. Bi Baba Kudi ba ni owo lowọ, oun ni ki o ronu bi o ṣe ko tirẹ jọ.

Mo rọ Olootu lati maṣe maa gbe iwe bi iru eyi ti Ajani baba Kudi kọ yi jade mọ nitoripe ko dara. Mo si bẹ Olootu ki o ma binu ọrọ ti Baba Kudi sọ si i, ki Olootu mọ pe, "Otitọ koro".

Emi ni,
Amọdu Akanbi,
Eko

## Tinuola jade l'aiye

NI ọjọ kinni oṣu karun ọdun yi ni awọn ọmọ, ẹbi ana ati ọrẹ sinku Iyaafin Tinuọla Alake Agbo, lẹhin ti o ti lo nkan bi aadọrun ọdun l'aiye ki o to fi ilẹ bora bi aṣọ.

Ni agbo ile Atunlakatẹ, adugbo Abogunde nilu Ogbomọṣọ ni inawo oku gbe waiye.

Ọpo omo ati omo— omo l'o gbẹhin oloogbe na. Ara won ni David Alagbe, arabinrin Ọmoyẹmi Anikẹ, J hn Alabi, David Ayinde, Sunday Atanda, Solomon Adisa, Samson Amoo, Alice Ajogbe, Ruth Ajoro, Aderinola Aṣabi, Ajo—gbe; Ajadi ati S.A. Ajayi.

Awọn ọmọlooku na fi jije ati mimu tẹ awọn abanikẹdun ọjọ na l'ọrun.

Diẹ t'aye wa fun ninu wọn ni Solomon Ọladejọ Akọgun; Gbọlahan Lajide, Jimọh Olupo ati bẹẹbẹẹ lọ.

## Oluranti Tip

**14, 19, 48**

**22 23 25 40 50**

## Egbe Imole Owuro

12,500 Kẹhinde Ọdẹdiran, Ibadan
12,501 S. A. Fakanlu, Imẹsi-Ile
12,502 Oyeniyi Balogun, Omu-Aran
12,503 Fakayọde Akinlẹyẹ, Ibadan
12,504 Francis A. Philip, Eguntedo
12,505 Yisa A. Vasco, Oke-Onigbin
12,506 Ahmed Ọlayiwola, Ijaiye Orile
12,507 S. A. Ogunyinka, Abẹokuta
12,508 Matthew Ewuọla, Ibadan
12,509 Olufẹmi Ọdẹtọla, Abeokuta
12,510 Alhaji Basheer, Ibadan
12,511 Rabiu S. Owolarafẹ, Gbọngan
12,512 Salimọnu Yussuf, Jos
12,513 Toyin Adeyẹmi, Ijebu-Ifẹ
12,514 Wahabi Ramọnu, Okeya-Ipo
12,515 T. R. Babalọla, Ibadan
12,516 Simon O. Babayẹmi, Ikóle—Ekiti
12,517 Tajudeen Lamidi, Iwo
12,518 Peter O. Afọlabi, Shaki
12,519 David O. Julius, Ado-Odo

FUN IGBEGA EDE ATI AṢA YORUBA DI

**Omo Egbe Imole Owuro**

Iwe Idi Ọmo Ẹgbẹ)

Oruko rẹ.............................................

Adirẹsi rẹ............................................

Ọmọ Ilu ti o jẹ.......................................

Jawe yi ki o si poosu rẹ si
DOKUN AJADI
(Akowe Ẹgbẹ)
P.M.B. 5230, Ibadan.

# Alhaji Abinuwaiye wo agbo Hausbunalau

Lati Owo Bolaji Babalola



ALHAJI BAṢIRU ABINUWAIYE
Onigoje Aramọnda

ALHAJI Basiru Abinuwaiye ati ẹgbẹ alare Sakara Exponent rẹ ni a gbọ pe Ile Iṣẹ aṣe awo rekọọdu HASBUNALAU RECORDS CO. ni yio maa tẹ awọn rẹkọọdu ẹgbẹ alare Sakara rẹ jade fun igbadun araiye.

Mo gbọ pe laipẹ yi ni Ile-Iṣẹ HASBUNALAU RECORDS CO. ati ẹgbẹ Alare Sakara Alhaji Abinuwaiye pari eto lori ajọṣepọ yi ni ilu Eko.

Ẹni ti o sọ eyi di mimọ fun mi gbọ ni Ọga Agba nile-Iṣẹ Rekọọdu Husbunalau, Ọgbẹni Aṣamu Aminu, ẹni ti o sọ pe, Alhaji Abinuwaiye ti ṣe are aladun kan ti o ga lọla pẹlu goje aramọnda, eyi ti awọn yio gbe jade laipẹ yi.

Ninu ọrọ tirẹ, Alhaji S. Iṣọla ti iṣe Alakoso Ile-Iṣẹ Hasbunalau Records Co. fi ye mi pe, eto Ile-Iṣẹ oun ni lati maa ṣe awari awọn ọdọmọde oṣere ti Ọlọrun fun ni ẹbun orin kiko, ki awọn si ṣe iranlọwọ ti o tọ lati fi ẹbun wọn na han araiye nitori ki ẹbun na ma baa parẹ mọ wọn ninu, ki awọn na le di olokiki kari aiye ninu are yowu ti awọn ba ni ẹbun rẹ.

Nigba ti mo lọ si ọdọ gbajumọ Alhaji Abinuwaiye lati fi ọrọ wa a l'ẹnu wo nipa ajọṣepọ rẹ pẹlu Ile-Iṣẹ Hasbunalau, o fi ye mi pe, awọn gba lati wọ inu agbo awọn oṣere Ile-Iṣẹ Hasbunalau nigba ti awọn na ti ṣọnu gidigidi nipa eto na ti awọn si fi oju inu wo iru ipo ti Ile-Iṣẹ na wa l'ẹnu igba ti wọn ti da a silẹ.

O ni irohin nipa iwa otito ati ododo ti awon ngbo nipa Alakoso ile-iṣẹ na Alhaji Iṣọla dun mo awon ninu pupọ, bẹẹ ni awon tun ti ilosiwaju ati igbega ti o wa fun awon oṣere Ile-Iṣẹ Hasbunalau Records eyi ti awon na ni igbagbo pe, pẹlu Ogo Oluwa lẹhin ti awon na wo inu agbo Hasbunalau yi, orire nlanla ni yio jẹ fun ẹgbẹ alare oun na.

ITAN ṢOKI

Alhaji Abinuwaiye ti bẹrẹsi ṣe are Sakara lati nkan bi odun keje sẹhin (1971-77) ilu moka si ni kaakiri ilu Eko ati agbegbe rẹ, bẹẹ na ni won si npe e ni alare kaakiri awọn ilu bi Ibadan, Abẹokuta, Ijẹbu-Ode, Ẹpẹ ati ni Kutọnu nibiti nwon ti gbadun are re dọba ti o fi je igbagbogbo ni o maa nṣere fun won nibẹ.

Omo Ibilẹ ilu Eko Akete ni Alhaji Baṣiru Abinuwaiye, are Sakara si jẹ ajogunba fun un nitori baba rẹ Oloogbe Amusa Abinuwaiye ti Ẹpẹtẹdo jẹ olokiki onisakara nigba aiye rẹ.

A o ranti pe Ile Iṣẹ Hasbunalau Record yi ni o nṣe rẹkọọdu Adewọle Oniluọla, Vasco Dagama, alare juju: Wahabi Eiire (Aghada owo) ati ẹgbẹ alare Fuji rẹ.

B a k a n n a ni awọn alare ilẹ Kongo (Zaire) wọnyi ko jẹ kọka ile-iṣẹ na kere. Awọn ni: Orchisre Veve labẹ Olori wọn Kiamuagiwna Meteta, Crehestre Imperial Tropical Fietta, Centra African Fempire labẹ Oloye Dorchestre ati O.T.F. Band of Congo (Sammy Dikila) ati Jimmy Cocokan Ogbe lati ilu Idoma ni ilẹ Naijiria.

Olupinja awọn rẹkọọdu ti Ile-Iṣẹ na ṣe ni: Hasbunalau Trading Company, ni adugbo Balogun nilu Eko.


KEREO

GBOGBO - ENIA!

fun

*Ipolowo oja ati Ikede,
*Akiyesi ati Itufọ,
*Iranti oku ati Ikede Ariya,
*Ikilọ ati bẹbẹ lọ;
*Tabi Almanak ati Kalẹnda tite.

DARAPỌ PẸLU AWỌN OLOGBON ENIA TI O NSEE SI INU (IMỌLẸ OWURỌ) TI O GBAJUMỌ KARI AIYE. OWO TI A NGBA KOPO.SA KỌWE TABI KI O WA RI:-

Advertisement Manager:

IMOLẸ OWURO
N4/496B YEMETU ALADORIN,
P.M.B. 5230, IBADAN.


## Lawal Alagbe saisi

(Lati Oju Ewe Keji)

Islam ni ilu na.

Ẹgbẹ Shamusi-deen, ẹbi ati ọrẹ pẹlu awọn ọmọ oloogbe na ni o ṣe gbogbo akitiyan na. Alhaji Kalilu l'o ṣiwaju isin ikẹhin na.

Ọpọ ọmọ ati ọmọ-ọmọ l'o gbẹhin oloogbe na. Ara wọn ni Ganiyu Lawal, Surajudeen Lawal, Abdul Wahabi Lawal, Gasaliyu, Kassimu, Akimu, Khadijatu, Wosilatu, Amudatu, Nusiratu, Tayewo, Sidikatu.

Ara awọn ẹni nlanla, ẹlẹgbẹjẹgbẹ, ara, ọrẹ, ana ti o wa sibẹ ti nwọn si nawo nara nibi oku na ni:

Oloye M.M. Ajala, Oloye S. L. O y e w ọ, Demi Ọkẹ, Ijọ Mọṣalaṣi Ọlayaaju, Nalende Ibadan, Ijọ obinrin Ṣhamusideen. I b a d a n, Ijọ obinrin Alasalatu Mọṣelasi Ọlayaaju, L. Ladimeji, J Ayankunle, Ọgbẹni Sunday. Alhaji J. A. Agbọmọjo l'o ṣe waasi lẹhin isinku.

# Gende lu gende pa nitori obinrin ?

(Lati Ojn Ewe Kinni) lori ti o ngbe ni 59c Opopo Molipa, Ijẹbu-Ode, ba oun ja, o si pa oun lara.

Ṣugbọn irohin fi ye wa pe nibi ti awọn Ọlọpa ti ngba ọrọ silẹ lẹnu okunrin na ni irohin de si ile iṣẹ Ọlọpa pe, ẹni ti onitọhun wa fi ẹjọ rẹ sun ti iku nile iwosan nitori ara ti o fi pa pupọ nibi ija na.

Gẹgẹ bi irohin tiwi, nihin ni awọn Ọlọpa ti mu okunrin ti o wa fi ẹjọ sun na silẹ lati koju ẹjọ ẹsun ipania.

Ni adugbo ọna Molipa/Degun ni ija na ti ṣẹlẹ gẹgẹ bi a ti gbọ, awọn Ọlọpa si ti gba ọrọ silẹ l'ẹnu obinrin orekelẹwa ti ija ti ori rẹ ṣẹ, bẹẹ ni iwadi Ọlọpa l'ori ọrọ na ntẹsiwaju.

# Gambari ka Adajo lehin

(Lati Oju Ewe Kinni)

Irohin fi ye wa pe, Adajọ na fi ara rẹ han gẹgẹ bi ọkunrin ninu ijakadi na bi o tilẹ jẹ pe ẹni ti o mu ọbẹ lọwọ ni o nba jagun. Ṣugbọn ninu idigbolu na, ọkan ninu ehin Adajọ na yọ sọnu, ete rẹ si wu.

Bayi, ọwọ awọn Ọlọpa ti tẹ ọkunrin ti nwọn sọ pe o daran na, nwọn si ti da a duro si ile iṣẹ awọn Ọlọpa ni Agodi Ibadan fun iwadi.

# Tokotiyawo dagun faiyawo

ṢỌNBỌLỌKU ni tọkọtiyawo kan bọsọwọ awọn oṣiṣẹ Onibode ni papa ọkọ ofurufu Muritala Mohamed, Ikẹja ni ipari ọsẹ ti o koja nigba ti nwon gunlẹ si papa oko ofurufu na pẹlu idi leesi mẹrinlelogun.

Gẹgẹ bi a ti gbo, nwon ni lati ilu London ni ilẹ Gẹẹsi ni nwon ti nko leesi na bo lati fi ṣe ayẹyẹ igbeyawo won ti o sunmole.

Irohin sọ pe bi awọn tọkotiyawo na ti ngunlẹ ni budo oko ofurufn na ni ọwọ tẹ wọn.

A gbọ pe awọn oṣiṣẹ onibode ti gba leesi na silẹ, nwọn si gba ọro silẹ l'ẹnu awon enia na.

# POOLS

10 2

18 11

38 13

Nap 2 15 39


# OLORIRE O! OLORIRE O!

AWA ẸGBẸ ONIṢOWO ONIṢẸ ẸRỌ TI NJẸ

## WESTERN NIGERIAN TECHNICAL COMPANY LTD

TI TUN GBE ERỌ ARAMỌNDA KAN DE. ẸRỌ NA NI A NPE NI



## Solo Lawn Mower (₦266.00)

(EYI NI ẸRỌ TI A FI NGEKO)

Meji iru ẹrọ yi ko si rara
Ni ilẹ Naijiria.
Bi oko ti le wu
Ki o kun tabi pọ to
Ko jẹ nkankan l'oju ẹrọ na,
Ni kiakia ni yio pari rẹ.
Iwọ ti o ni ọgba l'ayika ile rẹ,
Ati ẹnyin alaṣẹ ile iwe,
Ẹrọ yi ni ki ẹ maa lo.
O dun i geko pupọ,
O si ni alopẹ.
Owo ẹrọ na ko pọ rara
₦266.00 pere ni.
Tete wa ra tirẹ ni:

## Western Nigerian Technical Company Limited

P.M. B. 5148: PHONE 22361/2
DUGBẸ ONIMATIRẸSI, IBADAN.

WENTEC 1955


Printed and published by the People's Star Press Limited, N4/496B Yemetu Aladorin P. M. B. 5230, Ibadan. Olootu (Editor) Lawuyi Ogunniran, E4/803, Aperin Adekile Ibadan. Lagos Office 18, Odunlami St, Phone 27017.